# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KẸRIN, ỌDÚN 2022**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸRIN 2022

## DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN ẸMÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (2)

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

1. Ẹ̀mí Mímọ́ dé lọ́jọ́ Pẹ́ntíkọ́stì,
Ó dé pẹ̀lú agbára nlá,
Ẹ̀rí Rẹ̀ sì yí ẹlẹ́sẹ̀ padà,
Ọ̀pọ̀lọpọ̀ di àtúnbí,
A tú àwọn Krístíàn kákírì,
Wọ́n wàsú Jésù láíbẹ́rù,
Púpọ̀ ni wọ́n sì fẹ̀mí wọn lélẹ̀, nwọ́n tẹ̀sìwájú sì ṣẹ́gun!

Ègbè: Wá Ẹ̀mí Mímọ́, Òkùnkùn ṣú,
A nfẹ́ farahàn, Ìfẹ́ àt’agbára Rẹ̀,
Rìn lí àrín wa, Ru wá sókè,
Wá Ẹ̀mí Mímọ́, Sọ Ìjọ jí lónì!

2. Nígbà òkùnkùn tún bo ayé,
A n wàsú ìsọdímímọ́,
Ẹ̀mí Mímọ́ sì sọ ìjọ di àtúnbí,
Iná ìsọjí njó gere,

L’ọ́dún púpọ̀ sí ìsọjí nlá dé,
Àwọn mímọ́ sì n gbàdúrà,
Á lẹ́kàn si atún nfẹ́ iná,
Láti kojú sí ‘pèníjà!

Ègbè: Wá Ẹ̀mí Mímọ́, Òkùnkùn ṣú,
A nfẹ́ farahàn, Ìfẹ́ àt’agbára Rẹ̀,
Rìn lí àrín wa, Ru wá sókè,
Wá Ẹ̀mí Mímọ́, Sọ Ìjọ jí lónì!

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Bàbá mi, bí mo ṣe wà níwájú Rẹ lónìí, jẹ́ kí agbára Rẹ kẹ́gàn gbogbo àwọn tó n dúró láti gbọ́ ìròyìn búburú nípa mi, ní orúkọ Jésù.
2. Báyì ni Olúwa wí: “Kí ijòyè, agbára, aláṣẹ òkùnkùn, ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run tàbí ìwà ìkà ìbílẹ̀ máṣe yọ mí lẹ́nu mọ́, nítorí èmi nru àpá Ọ̀dọ́-Àgùntàn Ọlọ́run kiri lí ara mi,” ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, nípa àánú Rẹ, la ọ̀nà fún mi kúrò nínú gbogbo agìnjù wàhálà tí mo bá ara mi, ní orúkọ Jésù.
4. Agbárakágbára tí wọ́n yàn láti sọ ìrìn àjò ọjọ́ mẹ́wà mi di ọdún mẹ́wà, o kòní ṣerere; agbára Ọlọ́run yóò pa ọ́ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa àánú Ọlọ́run, àwọn agbára tí wọ́n yàn kó dójúti iṣẹ́ ọwọ́ mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fa ire kúrò nínú ayé mi, yóò ṣubú lulẹ̀ kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ẹ̀yin ángẹ́lì ogun, níbo lẹ wà? ẹ dìde, kí ẹ sì kẹ̀yìn àwọn ọ̀tá mi kọ ara wọn, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn agbára tó n kó àyídáyidà bámi láti ṣiṣẹ́ lòdì sí ara mi, jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára tó nlo anfàní àwọn aṣìṣe mi, já ìdè rẹ lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
5. Mo tú irètí àti èròngbà àgbà ìkà yòówù tí wọ́n yàn láti kó àyídáyidà bámi ká, ní orúkọ Jésù.
6. Agbára ìkà tí wọ́n yàn láti lo agbára búburú lòdì sími, Ọlọ́run, dìde, tú wọn ká sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn ọfà aba-ìyanu-jẹ́, tí wọ́n yàn lòdì sími, Ọlọ́run, dìde, tú wọn ká sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Rómù 8:1** Njẹ́ ẹ̀bi kò sí nísisìyí fún àwọn tí ó wà nínú Krístì Jésù, àwọn tí kò rìn nípa ti ara, bíkòṣe nípa ti Ẹ̀mí.

**Rómù 8:28** Àwa sì mọ̀ pé ohun gbogbo li ó nṣiṣẹ́ pọ̀ sí rere fún àwọn tí ó fẹ́ Ọlọ́run, àní fún àwọn ẹnití a pè gẹ́gẹ́ bí ìpinnu rẹ.

**Jòhánnù 16:33** Nkan wọ̀nyí ni mo ti sọ fun nyín tẹ́lẹ̀, kí ẹ̀yin kí ó lè ní àláfíà nínú mi. Nínú ayé, ẹ̀yin ó nì ìpọ́njú; ṣùgbọ́n, ẹ tújúká; mo ti ṣẹ́gun ayé.

**Òwe 10:28** Àbá olódodo, ayọ̀ ni yóò jásí: ṣùgbọ́n ọdún ènìyàn búburú li á ó ṣẹ̀ kúrú.

**1 Jòhánnù 5:5** Tani ẹnití ó ṣẹ́gun ayé, bíkòṣe ẹnití ó gbàgbọ́ pé Ọmọ Ọlọ́run ni Jésù ìṣe?

**1 Jòhánnù 4:4** Ẹ̀yin ọmọ mi, ti Ọlọ́run li ẹ̀yin, ẹ̀yin sì ti ṣẹ́gun wọn: nítorí ẹnití mbẹ nínú nyín tóbi ju ẹnití mbẹ nínú ayé lọ.

**Jòhánnù 1:5** Ìmọ́lẹ̀ nà sì nmọ́lẹ̀ nínú òkùnkùn; òkùnkùn ná kò sì borí rẹ̀.

**Orin Dáfídì 9:2** Èmi ó yọ̀, èmi ó sì ṣe inú-dídùn nínú Rẹ̀, èmi ó sì kọrin ìyìn sí orúkọ Rẹ, Ìwọ Ọ̀gá-ògo jùlọ.

**Ìfihàn 3:5** Ẹnití ó bá ṣẹ́gun, òn ná li á ò fi aṣọ funfun wọ̀; èmi kì yóò pa orúkọ rẹ̀ rẹ́ kúrò nínú ìwé ìyè, ṣùgbọ́n èmi ó jẹ́wọ́ orúkọ rẹ̀ níwájú Bàbá mi, àti níwájú àwọn ángẹ́lì rẹ̀.

**1 Tímótéù 6:12** Má ja ìjà rere ti igbàgbọ́, di ìyè aìnípẹ̀kun mú nínú èyítí a gbé pè ọ́ sí, tí ìwọ sì ṣe ìjẹ́wọ́ rere níwájú ẹlẹ́rì púpọ̀.

**1 Pétérù 5:8** Ẹ má wa li àìrékọjá, ẹ ma ṣọ́ra; nítorí Èṣù, ọ̀tá nyín, bi kinìún tí nké ramúramù, ó nrìn kákìri, ó nwá ẹnití yóò pajẹ kiri:

**Orin Dáfídì 103:5** Ẹnití ó fi ohun dídára tẹ́ ọ lọ́rùn: bẹ́nì ìgbà èwe rẹ di ọ̀tun bí ti idì.

**Númèrì 13:30** Kálébù sì pa àwọn ènìyàn lẹ́nu mọ́ níwájú Mósè, ó sì wípé, Ẹ jẹ́ kí a gòkè lọ lẹ́kàn, kí a sì gbà á; nítorípé àwa lè ṣẹ ẹ.

**Lúkù 11:22** Ṣùgbọ́n nígbàtí ẹnití ó lí agbára jù ú bá kọlù ú, tí ó sì ṣẹ́gun rẹ̀, á gba gbogbo ìhámọ́ra rẹ̀ tí ó gbẹ́kẹ̀lé lọ́wọ́ rẹ, á sì pin ìkógun rẹ̀.